## Awọn ofin lori ìwà ìbálòpọ̀ fun awọn òṣìṣẹ́ afẹ́dàáfẹ́re

Òṣìṣẹ́ afẹ́dàáfẹ́re**, a le ba won wi - ko da, ale dawon duro -lati ipase awon iwa aláìbẹgbẹmu tabi ti ko boju mu ti o je mo iwa ibalopo**. Awọn wọnyi ni awọn ofin ti wọn gbọdọ tẹ̀lé:

- Awọn òṣìṣẹ́ afẹ́dàáfẹ́re **ko ni anfaani lati ni ajose ibalopo pẹlu ẹnikẹni ti ko i ti pe odun mejidinlogun, koda ti ofin orilẹ-ede wọn ba fi aye iru e sile.** Siso wipe awon ko mo iye omo odun o ni toun je àwíjàre tí kò lẹ́sẹ̀ nílẹ̀.

- Awọn òṣìṣẹ́ afẹ́dàáfẹ́re **ko ni anfaani lati tan oran ibalopo pelu owo, igba ni sise, ojà tàbí iṣẹ́** –ni paa paa oja ati ise ti a ti pero lati lo gegebi ohun iranlowo fun awon alaini. Won ko gbodo lo ileri awon nnkan wonyii lati tan awon eniyan je de ibi pe won yi o fi ara mo awon iwa ti o mu idoju ti ba won tabi rẹ́ won jẹ. eleyi ni i se pelu sisan owo tabi fifi isanwo lo oni nabi tabi Asewo.

- Awọn òṣìṣẹ́ afẹ́dàáfẹ́re nípa lórí eni tin je anfani ọjà tàbí iṣẹ́. Èyí fi wọ́n sí ipò agbára lórí àwọn tí ó nílò ìrànlọ́wọ́. fún ìdí èyí, àwọn àjọ afẹ́nifẹ́re **rọ àwọn òṣìṣẹ́ wọn láti máà ní ohun tí ó jẹmọ́ ọ̀rọ̀ ìbálòpọ̀ pẹ̀lú ẹnikẹ́ni tí ó ní ǹǹkan** n ṣe pẹ̀lú fífẹ́nifẹ́re. Irú àwọn àjọṣe bayii lè mú kí àwọn eto afedaafere dàbí èyí tí kò ní òtító nínú, tí kó sì ṣe é fi ọwọ́ sọ̀yà fún.

- Ti òṣìṣẹ́ afẹ́dàáfẹ́re ba **ri oye ti ko fi ni lokan bale tabi ti o fura** pe ẹnikẹni ninu ajo wọn tabi ajo iranlowo miran ntapa si ofin to ro mo iwa ibalopo, won**gbọdọ** ṣe ijabọ rẹ, gegebi **ilana** iṣeto ti ajo won fi lele.

- Òṣìṣẹ́ afẹ́dàáfẹ́re **ni lati se idale ati amojuto eto** lati ni agbegbe ise ti ko fiaye gba awon isesi ibalopo ti ko boju mu ati wipe ki won gba awon osise won niyanju lati maa se amulo ilana gegebi won ti lasile ninu **ofin atoni sona. Gbogbo alakoso** ni ojúṣe lati se eto atilẹyin ati idagbasoke ti yi o je ki eyi seesee.

Awọn ilana IASC lori ipalara ati ibalopọ awọn obirin wa nibi:
http://www.pseataskforce.org/uploads/tools/sixcoreprinciplesrelatingtosea_iasc_english.doc.
èrò ẹ̀yà èdè àjùmọ̀lò kedere yii ni a gbe kale ni ifowosowopo laarin awon IASC lori sise àkọsílẹ̀ si awon eniyan ti o nilo iranlowo ati idabobo kuro ninu ibalopo ti o ni ireje ati ilokulo ninu pelu ajo Titumo lailopin.